# 142 *À Ń Wàásù fún Gbogbo Onírúurú Èèyàn*

## (1 Tímótì 2:4)

1. A fẹ́ máa fara wé Ọlọ́run wa,
   Ká jẹ́ ẹni tí kì í ṣojúsàájú.
   Ó fẹ́ kí gbogbo èèyàn rí'gbàlà;
   Gbogbo onírúurú èèyàn ló ń pè.

(ÈGBÈ)

*Ibi yòówù kí wọ́n wà;*
*Ọkàn ló ṣe pàtàkì.*
*À ń wàásù Ọ̀rọ̀ Ọlọ́run fún wọn.*
*Torí pé a nífẹ̀ẹ́ wọn,*
*À ń wàásù níbi gbogbo:*
*"Káwọn èèyàn lè dọ̀rẹ́ Ọlọ́run."*

2. Ibi yòówù kí a ti pàdé wọn
   Tàbí irú ẹni tí wọ́n lè jẹ́.
   Ẹni tí wọ́n jẹ́ nínú ni Jáà rí—
   Ìyẹn ló sì ṣe pàtàkì jù síi.

(*Ègbè*)

3. Jèhófà nífẹ̀ẹ́ àwọn tó pinnu
   Láti má ṣe jẹ́ apá kan ayé.
   A mọ èyí, a sì fẹ́ káyé mọ̀,
   Torí náà à ń wàásù fáwọn èèyàn.

(*Ègbè*)

(Tún wo Jòh. 12:32; Ìṣe 10:34; 1 Tím. 4:10; Títù 2:11.)

*snylpnw*-YR No. 142 5/15
© 2015 Watch Tower Bible and Tract Society of Pennsylvania